# JAMBA QKQ OFURUFU, ORIMOLUSI R'QRUN ALAKEJI


**Ikede**

Asetrode yi fun gbogbo ényin Okowe wa ati asoju wa wipe, éni kéni ti owo ba teku si owo re ki o tete fi ranse nitori gbogbo ohun elo ti a fi notewe irohin lo ti gbe owo leri.

Enikeni ti ko ba fi tire ranse ao da iwe re duro ao si sa agbara lati gba owo wa ni owo re. Olotu



# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO



LADIES BRASSIERES

2/-6d, 3/, 4/-6d & 5/-6d each.

Obtainable at:-

A. B AKINYEMI

10A, Moloney Bridge Street LAGOS.



VOL VII No. 434 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA SEPTEMBER 24 1955, IYE OWO ELETI OFE KOBO MEJI. (2)


## Won Si Ile Igbimo Ilu Epe



OLU EPE DI ALAKOSO IGBIMO

Ni ojo Monday ti ise ojo kokandinlogun osu yi ni nwon si ipade akose ti Igbimo Ibile ilu Epe–ese gbogbo awon Olugbimo si pe sibe sibasiba.

Nigbati oro de ibi ati yan enia si ipo Alaga ni oro na fere d'ogun d'ode nigbati awon Ijo Faramora so wipe ki awon dibo ni asiri fi yan enia awon Ijo Ijebu Parapo ko fe be, nwon so wipe ki awon yan enia na ni gedegbe ni. Gbogbo Ijo Faramora binu jade, oro ko wa loju mo.

Beni Oyinbo Ajele ti gba won ni Imoran wipe, gegebi bi o ti je pe enikan-soso pere ni Ijo Ijebu Parapo fi tayo Ijo Faramora eyi ko ni jeki nwon le se Ise Ijoba tara, ayafi ki awon Ijo mejeji sowopo fi ara won s'okan

Irohin ti a tun gbo ni wipe Oba Alayeluwa Olu Epe ni yio se Alakoso Ile Igbimo Ibile, Ogbeni Condie ni yio si se Alaga Ile Igbimo na

Bi eyi bari be, oro na wa tun e si baa niyen Bi oro ba dun orin ni a fi nko:-

Olu-Epe d'araba
O diji o ee
Olu-Epe d'araba
O diji o a a,
Gbogbo igi to mbe nigbo
Araba l'obori re,
Olu-Epe daraba o digi o a

Nje, Oba Alase ekeji Orisa Olu-Epe, a ba e yo.

## Oloye Rotimi Williams Ti Ajo De



Ni ojo Wednesday ti ise ojo kokanlelogun osu yi ni Oloye Rotimi Williams, "O yo fu , ba'gba l'eru" ba oko Apapa de lati ilu Oyinbo nibiti o ti lo gba olofe-ara die fun isinmi re.

E KU ABQ O


## Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ko to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

Medicine Store

7, Egerton Road, Lagos


## JAMBA QKQ OFURUFU

Agbo ju'gbanu ni irohin ti a gbo wipe oko ofurufu kan to nko ero lati ilu Oyinbo, ni Oba Alaiyeluwa Joel Adeboye, Orimolusi ti Ijebu Igbo to ti lo ba won se ipade ajoro ti awon Onikoko nilu Oyinbo wo lati pada sile.

Oko Ofurufu na ya nilu Romu, sugbon nigbati o de IDRIS, ti oko na fe so kale ni o fi kolu awon igi, lesekese ile epo fo, ina gba oju orun kan.

Enikansoso l'ofarapa pupo ninu awon to ye, afi awon ti nwon farapa die-die, nwon yara ko won lo si Ile Itoju Alaisan ti awon Oloko Ofurufu nilu IDRIS.

Ero ni awon enia metala ninu awon to ku, meji pere lo ku ninu awon osise inu oko Ofurufu na. Ogoji ni ero ti oko na ko awon osise inu re je meje.

A ko ri oruko Oba Orimolusi ninu awon to m'ori bo ye ninu jamba oko yi.



QGBENI ANDREW YOUNG

Aworan yi niti Qgbeni Andrew Young ti ise Alaga Igbimo ile ise owo sise nile yi (Chairman of the Nigerian Central Marketing Board) ti o je okan ninu awon ero inu oko na ti re, ti gbogbo won je enia metadinlogbon to ye ninu ero to wo oko na,

A ki Qgbeni Young o ku Oluwa yo pelu awon elegbe orire!


## THE NATIONAL BANK

**OF NIGERIA LIMITED**

Ile ifi Owo pamosi yi
Nfi ona owo han eni
Bi o ba fe je onisowo pataki ao
ran o lowo nipa wipe ao to o
si ona ti o dara, ao la oju re
si Qna owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nse iranlowo fun
gbogbo oja ile wa ti anta si agbaiye.

ILE ISE WA NI EKO:-
37, MARINA, P. O. BOX 508, LAGOS.
AWON ASOJU WA NILU OBA NIYI:-
THE NATIONAL PROVINCIAL BANK
(Overseas Branch)
1. PRINCESS STREET LONDON E. C. 2.
THE COMPTOIR NATIONAL D'ESCOMPTE
DE PARIS.
8/13, KING WILLIAMS STREET, LONDON
E. C. 4.

# Nfe Iranlowo Lodo Ijoba Oke-Oya

Olotu,

Ojo wa laye lati fi wosika wa yi kesi Ijoba Oke-Oya fun iranlowo nipa Titi tabi oju opopo ona ilu Igbo-Nla eyiti a ti gbiyanju se ise ribiribi si oju opopo ona na.

Ise ona na ti rekoja si Ilia Orangun, awon ilu Igbo Nla nse wahala pupo lori ona yi. ona na yio si wulo fun Ijoba ati awon enia lopolopo, nitorina, a ke si Ijoba ki nwon lo rin ona na wo ki Ijoba si se iranlowo fun wa lori re.

Bi nwon ba ri ise ti a fi owo se si ona na, laisi-yemeji, a ni ireti wipe Ijoba yio gba oro wa ye wo.

A.O. Ogungbenle

I.A. Olaiyapo

Jimo Aweda (Igbimo Igbo Nla)

# Odun Metalelogorin Kuro Ni Kekere

Oba Alaiyeluwa Alake Abeokuta se ajoyo ojo ibi re, nigbati o di eni odun metalelogorin, o so ninu oro re wipe on ranti asiko ti Egba nse Ijoba funrawon ti ko sin si ede ti a npe ni Naijiria



Oba Alake so wipe lati nkan bi odun mejile-logota ti on ti mba won se'lu ati eto Ijoba, wipe opolopo iyipada ni o ti farahan nile Naijiria.

Oba Alake tun so wipe nigbati on ti di omo odun mokanle-logun ni on ti fi ara on jin fun ise ilu on, pelu gbogbo lasigbo aiye ti on ri, ayo ni o je fun okan on,

Ni pari-pari oro Oba Alaiyeluwa Alake ti ilu Egba yi, gbadura wipe ki Edumare sun emi on siwaju ki on le ri ojo na, ti Ijoba Naijiria yio di ti awon enia Naijiria fun awon enia wa.


## Iwora

Nigbati ara enia ba nfe gan Ohun ti o nfa a ni wipe nigbati Kidinrin enia ko ba sise deradara arun iwora yi ni ikilo fun oluwa re lati mo wipe Kidinrin ko sise to nitorina owo mbo ti enia ba nlo egbogi yi y lo ri alafia.

Ohun pataki ti o fa amodi wa fun enia ni wipe idoti po ninu eje oluwa re, lo dan egbogi De Witt wo fun ra re o le je ohun ti o nfe lo ra okan wo ninu sobu egbogi.



Ohun ti o nlu nigbati Kidinrin ko ba sise tara, sugbon bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio dexi oluwa re, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti sise. Danwo lo ra ni sobu egbogi.

DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles



WESTERN REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

## Stenographer Grade 11.

The Board invites applications from suitably qualified candidates for appointment as Stenographer Grade II.

Candidates should possess the Royal Society of Arts Certificate in shorthand for 80 words a minute and must be able to type at the rate of at least 40 words per minute. A good command of english is essential.

Salary will be in the scale £195 x 15 - 300 per annum.

Applications accompanied by relevant copies of Certificates/Testimonials should be forwarded to reach:

The Personnel Secretary,
Western Region Production
Development Board,
Ibadan.

not later than 5th October 1955. Only applications of those selected for interview will be acknowledged.



WESTERN REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD.

## STENOGRAPHER GRADE 1.

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment as Stenographer Grade I.

Candidates should possess the Royal Society of Arts certificate in shorthand for 100 words a minute and must be able to type at the rate of at least 40 words per minute. A good command of English is essential. Preference will be given to U. K. trained female applicants.

Salary will be in the scale £318 x 18 - 390; 414 x 24 - 486 per annum, point of entry depending on qualifications and experience.

Applications, accompanied by relevant copies of Certificates/Testimonials, should be forwarded to reach:

The Personnel Secretary,
Western Region Production
Development Board,
Ibadan.

not later than the 5th of October 1955. Only applications of those selected for interview will be acknowledged.



NOW,

AVAILABLE

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just write, Call, or
Phone 21372

IKORODU TRADING COMPANY

20/28, Balogun Street,
(P. O. Box 395) Lagos
AND
NEW COURT ROAD
IBADAN



AFUN NI L'OKUN ARA

Bi iwo ba ru (THIN) o le sanra ki o si l'okun lara to bi iwon okuta mewa de Ogbon tabi jubelo

A ti se awari ona eyi, kowe si wa, ki o si fi Sile meji (2/-) sinu iwe re lati so ara to fuyi di olokun-ara,

ADRESS:- ACTIVITIES,
KINGSWAY, (T140) DELHI- 9,
INDIA.


# Amotekun Wo Ilu Agunpopo

AGUNPOPO— Ariwo gba igun mererin ilu yi nigbati opo enia ri ogbologbo Amotekun ni opopo Idikan ti o mbo wa si arin ilu. Tomode-tagba nsa asala fun emi won nitori eranko buburu yi. lesekese awon ode ti o wa ni ilu yi ti maca nwon si sa gbogbo agbara won sugbon owo nwon ko te eranko yi ti o fi lo.

A gbo pe eranko yi ko se enikeni lese, sugbon o fi aguntan kan se etutu, o si gbe aguntan na lo bambam.

# Oye Olisa Ti Ijebu Igbo

Olotu
Gbami laye lati fesi si ohun ti omo Ladugbo ko laipe yi sinu 'Daily Times' pe Olori . O k e Sopin ni igbakeji oba Orimolusi ni Ijebu Igbo. O to ki enia wadi ohun gbogbo daju ki o ma ba pitan ti yio da rugudu sile.

Lati aro ojo ni Oke Sopin, Ojowo, Atikori O k e Agbo ati Japara, ti won papo di Ijebu Igbo, ti ni Olori lokokan, O b a Orimolusi, pelu Olisa, gebebi igbakeji re lo je Olori fun apapo gbogbo awon ilu mararun yi.

Nigbati ogun ati ote ko jeki won raye je Oba Orimolusi ati Olisa mo, a w o n Balogun ati Bale (Olori) lo nse akoso ilu, w o n s i p a ohun po pe ki Olori O k e Sopin ma se Alaga gbogbo apapose ipade, nitori O k e Sopin ni akoko tedo ni Ijebu Igbo.

Lati igbati a ti pada si je Oba Orimolusi ni a ti ni lati tun ma je Olisa, iran awon to si nje oye na wa pelu ohun ato won titi di oni

Oye Olori tabi Bale ilu kokan ko ni iran, enikeni ninu omo ibile ti ilu ba fe lo le gbe si aye na.

Ohun to to nisisiyi ni ki ilu se atunse bi ao ti se fi enia je si aye oye Olisa yi. O to pupo ni sa yi nitori ipo na yio je iranlowo gidigidi fun Oba Orimolusi ati Igbimo Ijebu Igbo ati fun ilosiwaju ati ire Ilu na.

Ki omo Ladugbo fi eyi kun imo re o. E se pupo fun aye ti e gba mi. Eo ma te siwaju o Ase!

OMO LIYAN.

won si ni lati duro nita. Oko Ayokele ko niye, awon atata enia si po nibi isinku na. Afo nla ni iku re si sile ninu Ijo ati ilu, ki Oluwa ko gbe si afefe rere. Aki awon omo ati ebi re ku ashinde o.

BO TI WA NI YIGI BENI NI GBANJA

Laipe yi ni a ba oku okunrin kan ti nje Sam Ijesha ni igboro Ile Ife. O dabi enipe a pa a ni, ona fun re si wa ni gige. Olopa ti da eni merin duro ni bibi loro titi ao fi ri idi oro na.

# Oba Ebumawe Be Ilu Eko Wo

Qba Alaiyeluwa Ebumawe ti Ago-Iwoye ni Ijebu, Qlola David Oshiyemi Fidigbadewa I ni o wa be ilu E k o w o n i akoko lati igba ti o ti de ori ite oba re ninu odun 1944,

Nigbati oba Ebumawe yi de si Eko, awon egbe omo i b i l e Ago-Iwoye, eka ti Eko se iyesi ribiribi fun Alaiyeluwa na, ni ile Agbon-magbe ni Yaba l'Ebute-metta,

Nibi ipade i y e s i t i nwon tun se fun Q b a Alaiyeluwa Ebumawe yi ninu Ilewe St, Judes ni Ebute-metta ni nwon ti so gongo oro to je mo ire ati ilosiwaju Ago-Iwoye, nse ni gbogbo re ndun yungba.

Oba Alaiyeluwa Ebumawe f i O l a r e l o f i k e si afinju Qba Alaiyeluwa Adeniji Adele II Oba Eko ni Iga Idunganran ni Isale Eko. Awon ibi pataki ti Oba Ebumawe tun be wo l'Eko ni Ile-ise Ero Asoro-Magbesi (N.B.S) ni Ikoyi, Ile Igbimo nla, I l e w e Kings College, Ile Iwosan Asewo-Sese, (Orthopeadic Hospital) ni Igbobi ati Ibudo Q k o-i l e (Railway Terminus.)

Awon Oloye to ba Oba Alaiyeluwa Ebumawe wa si E k o ni awon Oloye Qtunbabaruwa, Qtunbalewu, Qtunbayandiru Qtunba-Osepemiwa, Qtunbalegbere, ati I y a l o d e, Ago-Iwoye.

# Qgbeni J.K Adeyinka Rele

Laro ojo kefa osu yi ni Ogbeni Joseph Kofo. Adeyinka, opo kan ninu Ijo C.M.S. ti Oke Bola ati Oga Akoweta ni ojude Agbeni, jepe ikehin ni ile re ni Agbeni, O ni ailera fun Igba die sehin. Pelu bi ojo ti ro to beni enia se po to, tobe ti inu ile Ijo Pro-Cathedral ko gba won,

# Adelabu Faragba Ponwun Meta Siie meta

Ni ojo Satide to koja yi ni ojo ejo ti Ogbeni Henry Ajayi pe Ogbeni Adegoke Adelabu fun ponwun metale - logorin ni sisan lori Moto ayokele re ti o so wipe Ogbeni Adelabu baje lojo rogbodiyan Ode Oyo ni ojo karun osu September, l'odun to koja.

Nigbati Ogbeni Adelabu ko wa si Kotu wa je ejo yi lojo Satide, Adajo ni ki o lo san ponwun meta, sile meta fun Ogbeni Henry Ajayi fun aiko wa je ejo na, O si tun fi ojo na si ojo kerinlelogun osu September yi.


WESTERN REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

VACANCY FOR STORES ASSISTANT

Applications are invited from suitably qualified candidates for a vacant post of Stores Assistant in the Stores Section of the Board. Salary will be in the scale £126 x 6 - 132 x 12 - 180 per annum; point of entry depending on qualifications and experience.

QUALIFICATIONS

Applicants must be thoroughly conversant with Store rules and procedure in respect of vehicle spare parts and engineering equipment. Preference will be given to applicants who understand protective treatment methods and are able to select Bedford, Land Rovers and Ferguson vehicles spare parts.

Applications accompanied by copies certificates and at least two recent testimonials should be addressed to;-

The Personnel Secretary,
Western Region Production Development Board,
Secretariat, Ibadan

to reach him not later than 30th September, 1955. Only applications of those selected for interview will be acknowledged.

WESTERN REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

VACANCY FOR SENIOR STORES ASSISTANT

Applications are invited from suitably qualified candidates for a vacant post of Senior Stores Assistant in the Stores Section of the Board. Salary will be in the scale £318 x 18 – £390 per annum, entry point depending on qualifications and experience.

QUALIFICATIONS; Applicants must be fully conversant with Store rules and procedure. Preference will be given to candidates who possesses a thorough knowledge of vehicle spare parts in respect of at least one of the following: Bedford, Land Rovers, Ferguson Tractors and Trailers.

DUTIES:

The selected candidate will be required to undertake, in addition to general store keeping, duties connected with the safe custody of all Board's vehicle spare parts. He will be responsible for the selection vehicle spare parts and engineering equipment and will be required to enter into a Bond with the Board.

Applications accompanied by copies of certificates and two recent testimonials together with names of Bondsmen should be addressed to:

The Personnel Secretary,
Western Region Production Development Board,
Secretariat, Ibadan.

to reach him not later than 30th September, 1955. Only application of those selected for interview will be acknowledged.

E L E T I Q F E
A-NIU WON KO SE WI L'EIQ
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS
28! Kosoko Street, Lagos "ELETI-QFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL. VII NO. 434 LAGOS SATURDAY SEP. 4 1955.

# Ogun Agbotele Ko Ni Pa Aro

Gbolohun oke iwe wa yi l'o jade l'enu wa nigbati a gbo nipa ti opolopo ile ti awon Olutoju ilu so wipe awon ile na l'ewu fun awon enia to ngbe inu won.

Gegebi owe Yoruba to se wipe "Ogun agbotele ki npa aro" l'o mu wa lati ta awon enia wa ji nipa awon ile to l'ewu bawonni, wipe ki awon onile be mase afara lati se atunse si awon ile na, eyiti o ba fe ti tunmo, bi Onile ba kowe si awon Olutoju ilu wa (L. T. C) a ni ero wipe nwon yio gba won laye lati tunko tabi lati tun ile be se.

O ye ki a tete m'ojuto iru ile ti nwon ba ti ri wipe o ni ewu, paapa larin ilu wa yi, nitoripe awon Yoruba ni o so bayi wipe "Ina Esisi ki ijoni l'emeji" Isele ti o sele ni Ilewe St Peters, ti emi awon ogo-were fi yo s'orun lairo tele si gbona giri-giri l'okan wa.

E je ki a tete fi epo okowo j'aga o.




# Ipade Awon Babalawo Ni Iragbiji

O le ni edegbeta enia to wa si ipade ti awon Babalawo se ni ilu Iragbiji, ipade na je eyiti nwon ma nse ni osu meta-meta, Ile oloye Araba ti Iragbiji ni nwon ti se ipade na ni ojo kejo osu September, 1955 yi.

Ipade bere ni agogo mewa owuro, nigbati Awofesan ti o je asoju Araba ti Ile-Ife ni o se alaga, Ogbeni G. A. Odumade akowe awon Babalawo Oshogbo ni o ka iwe akosile ti ipade tokoja gbogbo won si fi ara mo Oloye A. A. Ajanaku. Araba Eko ati oloye Araba Makun fi oro Isiri ranse si ipade yi.

Larin oro ti nwon so ni eto bi odun Orunmila ti se ma je ojo kanna yipo ile Naijiria, nigbati nwon se onka won pinnu wipe osu August, 15, ni odun Orunmila yio ma bo si.

Lehin eyi, nwon yan enia mejila ti yio je Igbimo lati ma jiroro ohun ti nwon ba fe se, a wa mu ipade wa si ipari pelu jije ati mimu, Ijo ati ayo, nwon si jo lo si ile Oba Alaiyeluwa J. O. Iyodogun, Aragbiji ti Iragbiji eniti o se won ni alejo repete.

A fi ipade miran si ojo kejo osu December, 1955 ni ilu Ibadan. Opolopo awon to wa si ipade ni Adisa Shonibare, Abinbola Savage, ti Eko, Idowu Agbowo-ifa ti Ikorodu, Adebohun ti Abeokuta, Gbadebo Dusumu ati Okunola, ti Ibadan, Ososona ti Oshogbo, Fadare ti Ede, Elesin ti Gbongan, Fatokun Ile-Igbo, Amosu ti Telemu, Jogbodo ti Akiriboto, Ishadare ti Ipetu Monday, Lanloye ti Ogbagba, Esupidan ti Iragbiji, Ogunshigi ti Ikere, Makinde ti Fesu, Oyedeji ti Modakeke, Oyenuga ti Makun, Adenuga ti Ijebu-Ode Arifayo ti Ogere, Soleye ti Agbowa, Falobi ti Ara, Anifaleye ti Isbara, Fakunle ti Ejigbo, Fabowale ti Ifeodun, Odubawo ti Offin Shagamu Ogunleye ti Oyo, Aworanti ti Ada, Abioye ti kuta, Faranti ti Agba, Salako ti Ifon.

# Oku Qlomo Gege Lao Gbe

Ni asale ojo Jimo (Friday) ti ise ojo kerindinlogun osu September yi ni iya wa Moradewun Amope jade l'aiye nigbati o di eni odun marundin-logota l'ojo ori re, a si se isinku re l'ona ti Musulumi ni ojo Satide ti ise ojo k-tadin-logun osu yi. Lemomu Idita Alfa Ganiyu Thompson l'o se eto isinku iya wa na.

Ni ojo ose ti ase ase isinku iya wa yi, (Sitting Sunday) ni ojo kejidin-logun osu yi, ki o wa wo awon enia pataki-pataki to peju pese bi omi, beni inawo ojo na pa bambari, ti isinku na fi dabi eni nse igbeyawo.

Iya wa ti kosi yi je iya kekere (Aunt) fun Olotu ati Alakoso Ise Iwe Irohin wa Ogbeni Taju Thompson ti ise okan pataki ninu awon gbajumo Olugbimo fun itoju ilu Eko (Councillor of the Lagos Town Council.)

Ki a daruko die ninu awon saraki enia to wa sibi isinku na; awon enibi :- Ogbeni Bolaji Odunewu, Wahabi Balogun; A. S, Badru, S. A. Fashola, Y. A. Williams, Dodo Williams, Ayo Reffle, S. B. Bakare, I. A. S. Adewale, M. I. Adewale, L. R. Tokosi ati A. R, Amusa ati opolopo enia ti akole daruko tan.

Koye ki a ma daruko die ninu awon osise Iwe Irohin wa ti ese won pe sibi isinku na, awon bi S. Ademiju, Taofic Alade, W. A. S. Odebiyi, R. A. Subair, W. Adesina. A ko tun le ma so ti awon obinrin Eko mo, se enyin na mo wipe iru ni won, nwon ko je din l'obe - fun awon Ape Sindodo obinrin to dahiri.

Ki Edumare gbe Iya si afefe rere.

ASO ENIA KUKURU DI GUNGUN

Bi iwo ba nfe ki o gun die si (Increase Height) kowe fun "ILANA TO DAJU" lodo wa. O dara fun Okunrin ati Obinrin Fi Ogbon Sile (30/-) sinu iwe re, ibase Postal Order, Bank Draft tabi SEKI Ari rin-Ajo ti Gesi tabi America, Ao Gba.
ADDRRESS:-
ACTIVITIES (D 240)
KINGSWAY, DELHI-9, INDIA.

## Idibo Yan Enia Si Igbimo Ife Pari



### Olola Oba Oni Ile-Ife

Egbe Afenifere (Action Group) ni o pegede ninu ibo ti nwon di nile Ife, awon enia ti Olukuluku egbe ti o wole niwonyi:-

| | |
|---|---|
| A.G. Talaka Parapo | 31 |
| A.G. ti Ogbeni J.R. Oye | 6 |
| N.C.NC. | 10 |
| Modakeke | 4 |
| Awon to duro gede | 6 |
| Awon Egbe Mekunnu | 3 |

Ni oro kan Egbe Afenifere lo bori. Oba Alaiyeluwa Olola nla Adesoji Aderemi ti ise Oba Oni Ile-Ife ni yio je Alakoso Ile Igbimo na, nigbati nwon ba si ni ojo Keje osu October 1955.

## Akiyesi Pataki

Nipa iwe ti a ri gba lati owo enyin Okawe wa, a fe fi eyi so fun yin wipe iwe irohin wa Eleti-Ofe, Elede meji ni (Bilingual Newspaper) Ede Oyinbo ati Ede Yoruba, ni a fi rejista lodo Ijoba. Nitorina, a ko le se ki Ede Oyinbo ma si ninu re, sugbon a ko ni je ki o po to Yoruba.

Bi o ti je niyen o.

OLOTU

## Ko Si Eniti O Fe Ku Laipe Ojo

### Apa Kini

Lati Owo ESO IKOYI

Awon baba wa, laiye igbani ko nfe ki iku pa won bi kose wipe ki nwon ma be nile aiye titi gbere. Awon Irumole aiye igbani, ko nfe lo si orun, bi ko ba se pelu tulasi. A ti ri ka ninu iwe Alukurani ati Bibeli wipe, ko si eniti o lo si orun ti o si pada bo ri. Sugbon o je oro ti a ma nsaba gbo lenu awon Babalawo tabi awon Arokin wipe, enikan takun lo si Orun, o si ti Ikole Orun ro wa si Ikole Aiye, Bawo ni oro na ti runi loju to?

Nigbati mo fi ara bale wadi oro yi, mo kan Babalawo kan ni ile Ketu ti nwon npe ni Adebo-ri ohun-ti-mbe lajude Orun; e jeki a ge oro na ni kukuru. O so fun mi pe, titi di akoko ti a wa yi ni awon enia fi ntakun re Orun

Bi enia ba sun, ti o si lala, nibo li o mo wipe on wo, tabi kili ohun ti o gbe de ibe. Eniti nwon ko ba fun laye lati tete pada wa sile aiye, nigba na ni a nwipe, enia nse Ojojo tabi saisan, sugbon eniti nwon ba da joko si ohun, nigba na li a nwipe enia ku. Awon Iko Olodumare ni a npe ni Angeli li ede Oloyinbo.

Mo ni lojo kan, Olodumare ran Iko si gbogbo awon Irumole wipe, ki gbogbo awon Irumole patapata sare gun esin wa li ojo kan on nitoripe, oro kan wa nile Nigbati Orun-mila gbo ise yi, eru ba a gidigidi. O sare lo, o gbe Iporun re lule, o ri Ogbe-wonrin, o si bere si kiji bayi wipe:-

Baba Orogbo, Baba Osugbo
Ajana Magbo tiye-tiye
Awon lo difa fun Orumila
Lojo ti Olodumare ranse pe
Gbogbo Irunmole lode orun
O ni ki nwon yara gesin wa foju kan on
Odidi eran Agbo kan
Ati egbata owo eyo ni ebo
Ogbe-wonrin
"

A so fun Orunmila lojo na wipe, ki o ma ase gesi agbo yen ni ki o gun. Orunmila gbo, o ru, o tubo o se etutu.

Nigbati ojo pe, Orunmila gun eran agbo re, o nlo loju ona orun. Gbogbo awon Irunmole ti gun esin mba a loju ona, nwon ya sile. Bi awon ti nkoja lo beni nwon nfi Orunmila se yeye wipe ko lowo lowo lati fi ra esin, eran Agbo lo rira. Sugbon Orunmila papa nke si won wipe, bi e ba de'ohun, e ma ba mi wi fun won pe Eran Agbo yi ni ko tete rin nile.

Lehin ti gbogbo awon Irunmole ti bodi si orun tan ti nwon ti nreti Orunmila ti koiti de, Onibode Orun ti lekun. Nigbati o se ti Orunmila de enu bode, o kan ilekun Onibode jagbe mo wipe pada sohun. O si pada sile aiye.

Orunmila mu ekun si ekun igbe, o mu ohun si ohun iyere, o njo, o nkorin bo lati ajule Orun bayi wipe:-

Olodumare tikun, me wa
Sigidi mogba, Sigidi mogba si,
Olodumare tikun me wa
Sigidi mogba, Sigidi mogba si.

## As'ewon Dile Pada S'ewon

Okunrin kan to ti nlo si ewon nigba mokanlelogbon l'o tun pada lo s'ewon nigba keji-le-logbon ninu ose tokoja.

A gbo wipe Salami Akanbi yi ti nwo ewon lati odun 1925, iyen di Ogbon odun nisisiyi to ti nwo ewon bo, ki nwon to tun mu de iwaju adajo fun esun wipe nwon ri awon apo ikowosi ati awon nkan bawonni lowo re, ti nwon ko mo eniti o ni won.

Adajo ni ki o lo se Osupa mejidinlogun l'ogba ewon pelu ise asekara.

---

## Lowo Iku Waya Oluwa Rere Gbawa

Odomokunrin kan ti o nje S. A Bello, onise Ina Monamona ni ilu Ibadan ni a gbo wipe o ku l'owuro ojo Thursday ose tokoja nipa agbako jamba Waya Ina Monamona (Electrocuted) ti o se nibi ti o gbe ntun Waya Ina se ni opopo ona Kotu tuntun ni Ibadan.

Lowo iku ina Onimonamona, Oluwa rere gba wa.

---

## Onibara Ki iko Ore

Eyi ki se bi ti okunrin aro onibara kan ti oruko re nje Ojo Ogbomosho, ti a gbo wipe o lo sile Loya kan lo se bara, o ni ki nwon fun on l'onje. nwon si fun lowo, sugbon o ju owo na si awon to fun u.

Lehinna ni o wa bere si erke ebu ni sise, o si nu awon to ba l'ore, nigbati iyonu re papoju, won mu de iwaju adajo, ni awon ol pa ba so fun adajo wipe ieba pupo ni nwon ti nmu okunrin aro enia yi wa si Kotu fun iru ese kanna yi.

Adajo so fun wipe iri re se enia l'anu, ati pe iwa alaimore ni fun o lati ma bu awon to ba s'anu re, ti nwon si nta o l'ore. Nitorina, adajo pase ki Ijoba wa pada si ilu re.

---

## Ijoba Iwo Orun Nda Bira

Awon Agbe mesan ti Ijoba, Iwo Orun Nigeria ran lo si ilu Oyinbo ati ile Amerika ti padade pelu Olotu ise Agbe; Akinloye, Ni gbegbe ibiti won nde ni ekun ile Oyinbo ni won se won li alejo daradara, won si ye won si pupo. A ki von ku abo o.

---

## Ojojumo Li Ope Nga Si!

UYO Ni Ariwa Nigeria. ni awon omo Egbe U N.I.P ati A. G. gbaye lowo awon N. C.-N. C. ni idibo ti won se lose yi,

---


## KERE O!

OGBOMOSHO DUN ALMANAC 1956.

Yio jade fun tita ninu Osu October 1955 yi. Awon Aworan to wa ninu Almanac na niwonyi :-

Olola Awolowo, Olola S. L. Akintola, Oba Ejigbo, E. A. Ande (Jos) J. A. Adekola, M. A. Ladapo, Egbe Oba-bi-Olorun-kosi, Bibiani G. C. Olola S. O. Ogundipe, Alaga Council Ogbomosho, Ajadi Onilu Ilorin, A. B. Awolola ati awon opo Aworan miran ti a kole ko tan.

Tete fi owo tire ranse ki o to tan. Eyo kan 1/-3d, Mejila 13/- Postage 6d.

J. A. ARE - EGBE, P. O. Box 7, Ilorin.

---

## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

**Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.**

A ma je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode

**OMORELA BABY MIXTURE**

*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN 100 KAN)*

O wa lodo :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS

---

*Ẹ le gbọ gbogbo awọn orin ti ẹ fẹ lati inu*

# DECCA RECORDS

**Ẹ wa si itosi ibiti ẹ le gbọ gbadun**

**Ni**

# S. C. O. A. RECORD SHOP

**144, Victoria Street, Lagos.**

**Gbogbo awọn Onișowo ẹrọ-ikọrin (Records) ni o mọ ibiti a ti nta wọn papọ ni ile Apapọ Itaja wa**

**Ti a ti ko lọ si ile itaja wa ni**
**144, Victoria Street, Phone 20938**

S.C.O.A Record Dept.
P. O. Box 534, Lagos.

Ati ni gbogbo ẹka ile itaja S.C.O.A ti o wa kakiri ilu Nigeria.

## Agbako Ori Ede!



Irohin ti a gbo lati ilu Holland nile awon enia funfun ni wipe Qlola Alhaji Ahmadu Sardauna ti ilu Sokoto pelu Oba (Emir) ti ilu Gwandu fere se agbako iku nigbati Moto won sese.

A gbo wipe Moto meta ni jamba na sele le l'ori sugbon ko si eniti o farapa dabi alara ninu won.

Qlola Alhaji Ahmadu, Sardauna ilu Sokoto pelu awon enia re ti re koja si apa Iwo-Orun ile awon Jamanu.

## Ope L'oye Eru, Tosan-Toru

Alhaji Ramanu Bello, ti ise Asoju iwe Irohin wa yi nilu Port Gentil nile awon Faranse to, ti ilu Meka de fi eyi dupe gidie di lowo Olorun fun ore ti Olorun se fun awon omo ilu Ogbomosho ninu odun yi.

Alhaji Bello so wipe awon omo Ogbomosho merin l'o lo si Meka lati ile Faranse, Port Gentil, nwon si pada bo wa sile pelu alafia daradara, ope ni fun Olorun, a si tun be Oluwa ki o bawa se ilu wa ni ilu alubarika, ki a ko ere Oko dele.

A Pada De Ni 14:8:55

Ni ojo ti a pada de, awon enia to wa ko wa l'ona ri bi omi, awon Alhaji Lawani Bello, Alhaji Busari, Alhaji Raji, Alhaji Yusufu Ali, Alhaji Ibram Gue, Alhaji Abudu Loyi, ati awon ore ati ojulumo, Buari, Bello Fatay Bello, Salawu Ladepo, Y. Bamgbe

Awon obi wa ko niye awon Miniratu ati Seliatu Ajile pelu opolopo enia, awa ti a lo ti si bo lati Meka ni Alhaji Ramonu Bello, Alhaji Yesufu Saliu, Alhaja Ayisatu Adetoro atiAlhaja Ayisatu Agbeke.

Alhaji Lawani Bello ti ise Olori gbogbo omo ile Yoruba se ioawo pupo lojo na, on ni egbon Alhaji Ramonu, iya re si Ayisatu Adetoro: A ko le rohin idunnu awon obi, ati iyawo wa A dupe fun Olorun.

## Awon Egbe Akorin Yio Se Isin Idupe

Awon egbe akorin ti ile Isin Iranti Johnson ti Ijo Methodist, (Johnson's Memorial Methodist Church) ni Ikorodu yio se Isin idupe ni ojo ose ti ise ojo keji osu October, 1955 ni agogo mesan-abo owuro

Awon Ogbeni T Ola Idowu ti ise Alukoso egbe ati A Awolesi ti ise akowe egbe Akorin ti nse eto repete sile fun ojo yi nwon si ti fi opolopo Iwe-ipe ranse si awon enia

Oluwa ko mu ojo re o

## KERE O! OBINRIN KAN NWA OKO

Ape sindodo omobinrin kan nfe eniti yio se oko re. Okunrin ti o ba fe nilati je Oga atata nibi ise (Senior Service) ki o si ma gba owo geregere, ki o ni Moto Ayokele, ki o ni ibugbe ni ikawo re, ki ojo ori re mase ju ogbon-odun si marundin-logoji lo.

Ki okunrin na kowe pelu aworan re ranse si Olotu Iwe Irohin "Eleti-Ofe"


# LAGOS RACE CLUB

## OCTOBER MEETING

**SATURDAY 1st, SATURDAY 8th AND SATURDAY 15th OCTOBER, 1955.**

| | FIRST DAY | START |
|---|---|---|
| RACE No. 1 | Six Furlongs 50 yards Handicap Bottom Division | 3.00 p.m. |
| RACE No. 2 | Six Furlongs 50 Yards Handicap Bottom Division | 3.35 p.m. |
| RACE No. 3 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4.10 p.m. |
| RACE No. 4 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE No. 5 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5.20 p.m. |
| RACE No. 6 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5.55 p.m. |
| RACE No. 7 | Eight Furlongs Handicap Top Division | 6.30 p.m. |
| | SECOND DAY | |
| RACE No. 8 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3.00 p.m. |
| RACE No. 9 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3.35 p.m. |
| RACE No. 10 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 4.10 p.m. |
| RACE No. 11 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE No. 12 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 5.20 p.m. |
| RACE No. 13 | Polo Scurry | 5.55 p.m. |
| RACE No. 14 | Five Furlongs Handicap Top Division | 6.30 p.m. |
| | THIRD DAY | |
| RACE No. 15 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 3.00 p.m. |
| RACE No. 16 | Four Furlongs Handicap Middle Division | 3.35 p.m. |
| RACE No. 17 | Four Furlongs Handicap Middle Division | 4.10 p.m. |
| RACE No. 18 | Four Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE No. 19 | Four Furlongs Handicap Middle Division | 5.20 p.m. |
| RACE No. 20 | Vice Chairman's Prize Sixteen Furlongs Handicap | 5.55 p.m. |

## Moba Olome Yo

Ogbeni A Bello omo Ijebu Ishiwo ni o se ikomo-jade omokunrin titon ti Iyawo re bi fun ni ile re ni 49, Oluwole Street, l'Eko

Alhaji Ganiyu l'ose eto isomo loruko na, awon si fun omo na ni Abdul Marufudeen Obafemi.

O fere je wipe gbogbo omo Ijebu Ishiwo ile yi l'o pejo-pese sibi ikomo na, awon Ijebu Ishiwo ti ilu won wa pelu be sini awon Alhaji Amsatu, Egbe Ifelodun, Olola Asani Ogbeni Jerimi ati opo enia ti akole daruko tan.

Jije ati mimu pelu ijo ati ayo ni ti ile fi su.

Ki Olorun da omo na si

---

## Iku Ko Mo Oba, Ko Mo Olowo Beni Ko Mo Ijoye

Gboke ni a gbo iku Alhaji Alhasan Dantata, Olowo araku-yamu nilu Kano l'ok-Oya ti o sele lale ojo Tuesday ose yi.

Lesekese ti o ti dake, ni Oba (Emir) ilu Kano ti fi Olopa Ibile medogbon ranse si ile re, wipe ki nwon o lo se amojuto awon ohun ini re ki nwon ma si jeki enikeni raye fowo kan eru Alhaji Dantata.

Alhaji Alhasan Dantata, Ologbe yi ni eniti o koko haya oko Ofurufu (Air Plane) ti o mu lo si Meka pelu awon enia re nile Nigeria wa yi.

Oba (Emir) ilu Kano ti yonda ki nwon sin oku re, sinu ile re

---

## Enyin Awomoto Ni Iwakuwa

THE FAULTY DRIVER




Aworan oke yi ni o nfi iwakuwa ti awon awamoto ma fi nwa Moto han.

Enyin awamoto, e sora.

# SPORTS - TO - DAY

## Warri Versus Kano To - Day

by BASH. OLUKOTUN

When the Second Semi Finals of the Nigeria Challenge Cup Match begins to-day, fans will watch two Champions in action Warri (West) and Kano (North)

The latter won the Challenge Cup in 1953 after beating Dynamos in the finals of the Competition.

It is a gross mistake to forecast this match as none of the teams have been seen in action. Let us be there to see them.

---




---

## Oku Ti Nwon Pin Ogun Re Tun Pada Si Aiye

KANO:- Odomokunrin afoju kan ti a npe oruko re ni Garuba ni ilu kan ni ona Kano, okunrin yi je alagbe enia, gegebi awa na ti mo pe afoju nilati ma kiri ilu lati wa onje fun ara re,

Ni aipe yi ti okunrin yi nsagbe lo si ilu kan ti a npe ni Dambata leba Kano, lehin osu die ti afoju yi ti fi ilu re sile ni irohin kan awon omo ati ebi re pe afoju yi ti ku si ona irin ajo re,

Awon ebi ati awon omo ti o fi sile se inawo pupo, nwon jo, nwon yo, nitoripe afoju yi ti fi ohun ini daradara sile fun won.

Nwon sin oku yi gegebi asa won, lehin ojo die ti won sin oku yi tan, ni won si pin ogun re fun enikokan won, eniti owo to si, won fun u pelu,

Ki a ma fa oro yi gun lo titi ko ju ojo kefa ti nwon pin ogun afoju yi ni o yo si won kale, enu ya gbogbo awon enia ti won ti gbo irohin wipe o ti ku, o si so fun won wipe on ko ku rara. Lesekese, awon ore ati alabagbe, fun ni odo aguntan kan lati fi se sara fun ewu nla ti o koja lori re.

---

## Eleti-Ofe Kari Gbogbo Ile Nile Nigeria, Ati Ni'lu Okere Wa Polowo Oja Re Sinu Eleti-Ofe

Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 73370